# ÒMÌNIRA FÚN ÌSÀBALÉ ÀWỌN ỌFÀ IBI

## April 2021

**Ìwé Mímọ́ Kíkà Dáníẹ́lì 3**

**Ìjẹ́wọ́: Isaiah 54:17**

1. Ọlọ́run, dide, kí o sì fàtu ohunkóhun tí a kò gbiǹ nínú orí òkè iná àti iṣẹ́ ìyánu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí, bà lé orí òkè iná àti iṣẹ́ ìyánu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, jẹ́ kí agbára àláfíà àti ìtẹ̀síwájú, síji bo orílẹ̀-èdè yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run, dìde kí o sì fún wa ní àwọn olórí tó bẹ̀rù Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo ọfà sátánì, tí a ta sí mi, padà sọ́dọ̀ ẹni tó rán ọ, ní orúkọ Jésù.
6. Ọfà asálẹ̀ àti àwọn ìbùkún tó rù-hanngo, jáde pẹ̀lú gbogbo májèlé rẹ, ní orúkọ Jésù.
7. Ọfà àìsàn àti àmódi, tí a ta sínú ayé mi láti ojú àlá,padà sọ́dọ̀ ẹni tó rán ọ, ní orúkọ Jésù.
8. Ọfà, tó ń fa àwọn ọ̀tá mọ́ra láti fi mí sẹ̀lẹ́yà,gbiná, ní orúkọ Jésù.
9. Ọfà, tó ń fa àjọyọ̀ mi sẹ́yìn, jáde kúrò láyé mi, ní orúkọ Jésù.
10. Gbogbo àlàfo, tó wà láàrin ìbùkún mi tó kéré jù àti agbára ìbùkún mi tó ga jùlọ, padé, ní orúkọ Jésù.
11. Àwọn ọfà ìfisòfò, tí a ta sí mi, ta padà kí o sì fi ẹni tó rán ọ sòfò, ní orúkọ Jésù.
12. Gbogbo ọfà, tó ń darí àwọn ìbùkún mi sọ́dọ̀ ẹlòmíràn, ta padà, ní orúkọ Jésù.
13. Ọfà, tó jàmí lólè, di fífọ́ nípa agbára Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
14. Baba, sọ mí di bọ́ọ̀lù iná Ẹ̀mi Mímọ́ tí kò ṣe é kópá lòdì sí, ní orúkọ Jésù.
15. Ohunkóhun tí àwọn ọ̀tá lè ti máa lò láti kópá lòdì sí mi, di jíjó run nípa iná Ẹ̀mí Mímọ́, ní orúkọ Jésù.
16. Ògo mi, lọ́wọ́ àwọn tó fipá lòdì sí mi, di títú sílẹ̀, ní orúkọ Jésù.
17. Ọfà ẹ̀gàn, ìkórira àti ẹ̀sín, ta padà, ní orúkọ Jésù.
18. Agbára, tí kò fẹ́ kí ohun rere gbogbo tó ṣiṣẹ́ fún àwọn mìíràn ṣiṣẹ́ fún mi, kú, ní orúkọ Jésù.
19. Àwọn ẹni ibi, tí wọ́n fara pamọ́ láti sàjọyọ̀ ibi lòdì sí mi, àrá Ọlọ́run, kọlù wọ́n dójú ikú, ní orúkọ Jésù.
20. Ọfà ìpàdánù ńlá, tí a firánṣẹ́ símí láti jẹ́ kí ké, padá sọ́dọ̀ ẹni tó rán ọ, ní orúkọ Jésù.
21. Ọfà, tí a yàn láti jẹ́ kí n ṣe àṣìṣe tí kò ní ní àtúnṣe, ta padà, ní orúkọ Jésù.
22. Ọfà, láti ahọ́n àwọn àgbà ìkà, lòdì sí mi, túká nípa iná, ní orúkọ Jésù.
23. Ọfà àwọn ọwọ́ tí kò mókun, èmi kìí ṣe tìrẹ, ta padà, ní orúkọ Jésù.
24. Ẹ̀yin àgbà ìkà, ẹ gbọ́ ọ̀rọ̀ Olúwa, ẹ kó gbogbo oṣó yín kúrò nínu àyànmọ́ mi, ní orúkọ Jésù.
25. Ọfà gbèsè ti ètò ìsúná, tí a yàn lòdì sí owó-ọ̀yà mi, kú, ní orúkọ Jésù.

26. Gbogbo ẹ̀jẹ̀ àjèjì, lórí ayé mi, di píparẹ́ nípa ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
27. Ọfà òkùnkùn, tí a yàn láti sọ ibi omi tútù mi di aginjù, ta padà, ní orúkọ Jésù.
28. Gbogbo agbára sátánì, tó ń lo oru ibi láti fún àyànmọ́ mi pa, gbiná, ní orúkọ Jésù.
29. Gbogbo àjèjì òkùnkùn, tó ń gbógun tì mí, tó sì ń fi ọ̀bẹ lé mi, pa ara rẹ, ní orúkọ Jésù.
30. Agbára ìkà, tí a yàn láti fi mí rúbọ ní ọjọ́ ayọ̀ mi, fi ẹ̀jẹ̀ ara rẹ san án, ní orúkọ Jésù.
31. Ọfà òkùnkùn, tó ń jẹ́ kí ìsòro mi di ìsòro tó lágbára, túká nipa iná, ní orúkọ Jésù.
32. Ìwọ agbára, tó ń lo ojú ẹni mímọ̀, nínú ẹbí mi, láti fi ayé mi sòfò, súbú lulẹ̀ kí o sì kú, ní orúkọ Jésù.
33. Ọfà, tó ń jẹ́ kí n máa rí wàhálà àti ogun ní gbogbo ọ̀nà, padà sọ́dọ̀ ẹni tó rán ọ, ní orúkọ Jésù.
34. Agbára yówù, tó ti dá májẹ̀mú pẹ̀lú òrìṣà yówù, lòdì sí mi, di piparun, ní orúkọ Jésù.
35. Mo yọ ara mi kúrò láàrin ajọ àwọn ọ̀rẹ́ ẹgbẹ́ òkùnkùn, ní orúkọ Jésù.
36. Ọfà àṣìṣe, tí a ti yàn láti tì mí kúrò níbi ayọ̀ mi, ta padà, ní orúkọ Jésù.
37. Agbára, tó ń rán ọfà ibi sí mi ní ọjọ́ ayọ̀ mi, kú, ní orúkọ Jésù.
38. Ọ̀tá mi aláìnírètí, gba ìdájọ́ ẹ̀tẹ̀ àtòkèwá, ní orúkọ Jésù.
39. Gbogbo ohun tí sàba bo ọfà ibi nínú ayé mi, gbiná, ní orúkọ Jésù.
40. Ọfà ikú òjijì, èmi kìí ṣe ìjẹ rẹ, padà sọ́dọ̀ ẹni tó rán ọ, ní orúkọ Jésù.